Kongi Nap WK 4
6 7 8

ASIKO Bks Wk 4
11, 22, 25, 38,

ROSS BKS Wk 4
25x21

# Imole Owurọ

9 SEP 1974

UNITY NAPS
For 3 sure draws in Wk 5 try to see The Manager Unity Pools House, E4/226, Gbelekalẹ Ibadan.
See him with N5 before 2 p. m. on Saturday.
NAP WITH N5
2, 8, 21, 38

Ẹṣin Ọrọ Wa: "IMỌLẸ DE! OKUNKUN PARADA"

Independent Paper VOL. XIII No 653 SATURDAY AUGUST 24 – FRIDAY AUGUST 30, 1974 5K. (KỌBỌ MARUN)

# ẸRANKO DI ẸNIA MỌ ỌDẸ LỌWỌ

ỌRAN ko sunwọn ninu igbo kan ni ilu Illah l'agbegbe Asaba ni Ipinlẹ Ado-Ibinni laipẹ yi nigbati awọn ọdẹ kan ti nwọn nṣọdẹ imọdo (turuku) kiri yinbọnpa ọkan ninu wọn pẹlu ero pe ẹranko imado ni awọn pa.

Irohin lati ilu na fi ye wa pe ọkunrin ọdẹ ti iku pa na ni nwọn npe ni Emenim Ollor ti nwọn pe ni ọkan ninu Ogboju ọdẹ ilu na.

Enikan ti o mọ hulẹ-hulẹ ọran na fi ye wa pe o pẹ diẹ ti awọn ẹranko imọdo ti bẹrẹ si i ba ohun ọgbin jẹ ni agbegbe na, ati pe eyi ni o mu ki awọn ọdẹ ilu na ṣa araa wọn jọ lati gbogun ti awọn ẹranko na. Nwọn ni ẹgbẹ ọdẹ tilẹ sọ pe ọdẹ ti o ba da araa rẹ l'oju ni ki o ba wọn kalọ si "ogun" na nitoripe, imọdo ki iṣe ẹranko ti ọdẹ apeku-pẹiyẹ le baja.

Siwaju si i, nwọn ni gbogbo ọdẹ ilu na l'o sọ pe awọn to bẹẹ. Nwọn ni nigbati nwọn de inu igbo, nwọn pin araa wọn, nwọn si nwa awọn imọdo na kiri.

A gbọ pe nibiti nwọn ti nṣe eyi lọwọ ni nwọn ti ri imọdo kan, ni nwọn ba nkọ si araa wọn pe "ọlọtẹ mbọ", onikaluku si gbaradi.

Irohin sọ pe l'ojiji ni iro ibọn dun ti ọkan ninu awọn ọdẹ na si nsọ pe "Ọwọ tẹ ẹ!" Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo wọn lọ sibẹ, ṣugbọn dide ti nwọn debẹ, kaka ki ọwọ tẹ imọdo, ọkan ninu awọn ọdẹ na ni nwọn ba nilẹ ti "ọwọ ti tẹ"! ni jẹbẹtẹ ba gbe ọmọ le wọn lọwọ.

Irohin fi ye wa pe lati wakati na ni awọn ẹranko na ko ti ri ẹnikẹni dọdẹ wọn kiri mọ; awọn Ọlọpa Asaba si ti ko awọn ọdẹ tihin lọ sile iṣẹ wọn: iwadi si nlọ l'ori rẹ bayi.




KINI o wa ninu aworan ti o nwo l'oke yi ? Aworan na jẹ ti oriṣi stamps ipoosu iwe mẹrin ti nwọn ṣe lati fi ṣe iranti iṣẹ ifiweranṣẹ ni BOTSWANA. Wo aworan na daadaa ki oye ki o si ye ọ.

# Elejigbo be Imole Owuro wo

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ogunjọ oṣu yi ni Elejigbo Ejigbo Alaiyeluwa Ọmọwọnuọla Oyeyọde Ọyesọsin Keji bẹ ile iṣẹ iwerohin IMỌLẸ OWURỌ wo ni Yemẹtu Aladọrin nilu Ibadan. Oun ati awọn enia kẹnkẹ-kẹnkẹ lati ilu Ejigbo ni nwọn dijọ ṣe ibẹwo na.

Ninu ọrọ rẹ fun Olootu iwe irohin Imọlẹ-Owurọ Ọgbẹni Lawuyi Ogunniran: Alaiyeluwa na sọ pe iwe irohin Imọlẹ Owurọ jẹ ọkan pataki ninu iwe irohin ti oun ko le ma ka nitoripe oun nifẹ si oniruru eto gbogbo ti iwe na ngbejade.

Ọba Oyesọsin ẹni ti siso ede Yoruba da l'ẹnu rẹ gidigidi fi kun un pe ẹnikẹni ti o ba nifẹ si igbega ede ati aṣa Yoruba, ti o si fẹ irohin otitọ ati ododo ko gbọdọ ma maa ka Imọlẹ Owurọ.

Nigbana ni Ọba na kansaara si awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ na fun iyanju wọn gbogbo.

Ninu idahun ibeere kan, Ọba Oyesọsin sọ pe akoko ti lọ nigbati ilu kọọkan maa nwoju Ijọba fun eto ilọsiwaju gbogbo; o ni ọlọmu l'o ku ti o nda ọmu iya rẹ gbe bayi.

Nitorina, Ọba na tun kesi awọn enia rẹ lati mu eto iranra-ẹni-lọwọ ni ọkunkundun lati le fi ṣe ohun ti o jọju si ilu Ejigbo.

Siwaju si i, Ọba na, ẹni ti o ndari ọrọ na si gbogbo ọmọ ilu rẹ nile, l'oko, ati ni idalẹ, rọ wọn lati gbaruku ti eto owo ojule ti Ijọba gbejade nitori gẹgẹ bi ọrọ rẹ, "eyi ni yio tubọ mu ki bukaata Igbimọ Ijọba ilu kọọkan maa biiya si i ti nwọn yio fi le maa ṣe ohun ti o jọju saarin ilu."

Bakanna ni Ọba Oyesọsin kesi awọn enia rẹ lati lo anfani ẹkọ-ọfẹ kariaiye ti Ijọba Apapọ fẹẹ dasilẹ fun ilọsiwaju ilu wọn lẹhin ọla nipa riran ọmọ wọn sibẹ nigbayowu ti o ba ya nitori gẹgẹ bi Ọba na ti wi "Ẹkọ ni atupa ti a ntan lati riran ri oju ọna ninu igbokegbodo ọmọ enia fun igbesiaiye rere".

Ninu esi tirẹ, Olootu Imọlẹ Owuro dupẹ gidigidi lọwọ Kabiyesi na fun ibẹwo na; o wi bayi: "Ibẹwo yi ṣe mi ni kayeefi pupọ, nitoripe, ng

(Woju ewe kẹjọ)

## Apprentice Wanted

LEARN to become a succesful printer. Learn on mordern marchine with modern technique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary six & mordern III school leavers send them to learn the art of modern Printing, Marchine operating, and Book - binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/696 Yemetu Aladọrin,
Ibadan.

# Mase fi esin re ran iborisa lowo (1)

Lati ọwọ Alufaa Mudaṣiru Aliyu

IWAASU mi ọsẹ yi duro l'ori akọle na pe: "Maṣe fi ẹsin rẹ ran ibọriṣa lọwọ". Iwọ ti o gba pe Ọlọrun kanṣoṣo l'o wa ti o si ti gba Anọbi Muhammed (S.A W.S) ni atọna rere, o ko tun gbọdọ fi iyi ati aasiki ti Ọlọrun fun ọ ṣe ẹyẹ fun ohun elo ibọriṣa.

Fifi araa rẹ han nibi ti nwọn ba ti nṣe ọdun ibọriṣa bi ọdun egungun, ọdun oro, ati awọn ọdun ti o jẹmọ ibọriṣa gbogbo jẹ fifi ẹsin rẹ ṣe iranlọwọ fun ẹsin ibọriṣa.

Bakanna bi o ba lọọ woran wọn, tabi o gba awọn ọmọ ati iyawo rẹ l'aye lati maa lọọ woran wọn pẹlu jasi pe o fi idile rẹ ran ibọriṣa lọwọ niyẹn.

Ọlọrun sọ ninu Kuri ani Mimọ Suratu 28 aya 17 pe: "Ọlọrun pẹlu idẹra ti o ṣe fun mi emi ki yio jẹ oluranlọwọ fun awọn ọbun" (eyi ni awọn ti nwọn ṣe atako ẹsin Islam).

Jẹ ki ng ntun tẹ ẹ mọ ọ leti, ki o si jẹ ki o ye ọ pe, wiwa nibi ajọdun ibọrisa pẹlu tayatọmọ rẹ a maa mu ki inu awọn abọriṣa dun pe ohun ti awọn nṣe dara ni ẹ ṣe waa woran wọn.

Nitorina iwọ Musulumi ati Kristiẹni ti o jẹ ọmọlẹhin Mohammed tabi ọmọlẹhin Jesu (S.A W.S.) maṣe fi iwa tirẹ ran ibọriṣa lọwọ rara ki awọn obọriṣa le ronupiwada lati kuro ni ọna ibọriṣa wọn.

Bi abọriṣa ba mbọ oriṣa rẹ ti iwọ ko ba a lọwọ si i, ti o ko si woran rẹ, diẹdiẹ ni oriṣa rẹ yio maa kuro ni ọkan rẹ. Ṣugbọn nigbati ẹ ba bẹrẹ si i lọọ woran wọn, nṣe ni ẹsin na yio tubọ maa gbilẹ si i ni ọkan wọn.

Nipa bayi, iwọ nfi ẹsin tirẹ gbe ẹsin ibọriṣa ga ni, bẹẹni ẹṣẹ nla ni fnu ọ bi o ba ṣe eyi.

Anọbi Mohammed (S.A.W.S) sọ pe ẹnikẹni ti o ba ran Ọṣẹbọ lọwọ nigbati o ba nṣẹbọ rẹ, Ọlọrun yio jẹ iru ẹni bẹẹ ni iya ẹni ti o nran oṣebi lọwọ.

Nitorina, jawọ kuro nibi wiworan ibọriṣa; maṣe fi ẹsin rẹ ran ibọriṣa lọwọ.

## Ijinle Owe Yruba

(Fun ẹni ti nfẹ Ọgbọn, Oye, ati Imọ (8)
lati ọwọ lawuyi ogunniran

81. Ẹlẹwu l'ẹwu ẹiyẹ
Adaba ko dara bi orofo
Egbin dara l'ẹranko
Nini sunwọn l'ejo:
Ko s'eku t'o dara bi ẹgbara
Ko s'ibi t'Ọlọrun ko da olu si.

82. Ẹnu ti Igbin ba fi bu Oriṣa
Ilẹ ni yio fi kin.
Ẹni ba ju ni lọ
Nii f'ọwọ ọla gba ni l'oju.

83. Ẹkọ nwọle ni tiilitiili
Ewe njade firifiri
Ẹ tun sọ pe ara baba ko da!
Bi ara baba ba da nkọ,
Ṣe yio jẹkọ tewetewe ni?

84. Ẹni da eeru l'eeru itọ
Ọdalẹ ba ile ku
Ẹni ba dalẹ I i ba 'lẹ lọ ni.

85. Ẹni ba mọ 'ṣe okunkun
K'o ma da Oṣupa l'oro,
Ẹni ba ranti ọjọ atisun
K'o ṣ'ọmọ oku ọrun l'oore.

86. Ẹni fẹẹ wo iṣẹju akan
Yio ku s'eti ebute,
Ẹni fẹẹ ri atisun pepẹiyẹ
Gbese adi ni yio pa a;
Ọdẹ t'o nṣọ Olodumare
Ori ẹgun ni yio ku si.

87. Ẹṣin ta, ta, ta, o ku
Ẹnia rin., rin, rin, o sọnu
Iji ja o gbe odo,
Ole ja o gbe Oriṣa-oko lọ!
"A ko r'iru eyi ri"
Eru l'a fi nda ba ọlọran.

88. Ẹni t'o binu ki ọwọ bọ 'na
Ko nii duro de onipẹ
K'o too sare yọ ọ jade.

89. Ẹni ti yio ṣ'ẹbọ ki o ṣ'ẹbọ
Ẹni ti yio ṣ'oogun k'o ṣ'oogun
Iṣẹbọ-ṣoogun, Olunnagun ni:
"Bi a ti waiye waa ri l'a a ri".

90. Ẹni pe, oṣupa ko gun
K'o nawọ ki o tun un ṣe.
A ti f'oje bọ Oloriṣa lọwọ
O ku ẹni ti yio bọ ọ.

## 'Club 25' be omo alainiya wo

Ni ọjọ kẹrinla osu yi ni awọn ọmọ Ẹgbẹ kan ti njẹ 'CLUB 25' nilu Ibadan bẹ ile awọn ọmọ a'ainiya wo lati fun wọn lẹbun.

Ninu ọrọ rẹ fun awọn ọmọ na, Akọwe Amuludun fun Ẹgbẹ na Ọgbẹni Dapọ Yussuf sọ pe, inu awọn ọmọ ẹgbẹ oun dun lati bẹ wọn wo gẹgẹ bi Ọmọ Ẹgbẹ ti o nwa alaafia ati idunnu enia gbogbo.

Ọgbẹni Yssuf fi kun un pe, oun ko wulẹ nii maa potobo ẹnu l'ori bi Ẹgbẹ oun ṣe ni ifẹ awọn ọmọ na lọkan to, ati bi awọn ṣe nfi adura ran wọn lọwọ nigbagbogbo, o ni ṣugbọn awọn wa lati fi iwọnba ẹbun diẹ ta wọn l'ọrẹ ni.

Siwaju si i, Ọgbẹni Yussuf sọ pe o wu ẹmi awọn lati fun wọn ni ẹbun ju bẹẹ lọ, ṣugbọn o ṣe ailera fun ara awọn nitori ailowo lọwọ ẹgbẹ tobẹẹ - ju - bẹẹ lọ ni akoko na. O ni ṣugbọn oun l'ero pe nwọn yio fi tayọtayọ gba ẹbun na.

Nigbana ni Ọgbẹni Yussuf ṣe ileri l'orukọ Ẹgbẹ na pe, awọn ọmọ na yio tun maa ri ọwọ Ẹgbẹ oun ju bayi lọ l'ọjọ iwaju, o rọ awọn ọmọ na lati maa huwa rere si awọn olutọ wọn, ati pe nkan wọnyi ni yio maa jẹ inudidun fun awọn enia gbogbo ti o fẹran wọn.

## Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

10,927 Lasisi Ọmọtitun Oṣogbo
10,928 Joseph Ọpalẹyẹ, Awẹ
10,929 Kọla Adekọla Adex, Iree
10,930 Ọlarewaju Ṣọdunọla, Shagamu
10931 M. O. Alao Ibadan.
10,932 Ọlawale Bello, Kwara
10,933 Fatai Gbada-mọṣi, Ibadan
10,934 Fasansi Adewuyi Ile-Ifẹ
10,935 J. O. Afọlabi Ogbomọṣọ
10,936 Ramọta Yusuf, Ogbomọṣọ
10,937 Tiamiyu Yusufu, Ogbomọṣọ
10,938 Olukayọde Ojo, Ifaki-Ekiti
10,939 Kọlapọ Fatanmi Irẹsi
10,940 Joseph Aiyedun, Ibillo
10,941 Joseph Ogun-niyi, Ogbomọṣọ
10,942 Adeniyi Baṣiru, Ogbomọṣọ
10,943 Ẹniafẹlamọ Aladiẹ, Kwara
10,944 Adepọju Awo-pẹtu, Ileṣa
10,945 Ọlabiyi Lasisi, Ọyọ
10,946 Rihanatu Aṣakẹ Ẹdẹ
10,947 Tunde Ọmọwumi, Ọyọ
10,948 Musa Ọmotoṣo, Kwara
10,949 Ramoni Lasisi, Ibadan
10,950 Yẹkini Atunde, Mọloko
10,951 Abudu Brown, Abẹokuta
10,952 Fẹhintọla Anthony, Ikarẹ
10,953 Rasaki Ọlaitan, Mọloko
10,954 Amidu Akanbi, Ẹdẹ
10,955 Lasisi Salami, Igboho-Irẹpọ
10,956 Olubu Adeloye, Abẹokuta
10,957 Moṣọba Popoọla, Ẹgbado
10,958 J. F. Olawuyi, Ogbomoṣọ
10,959 Samuel Kayọde Oṣogbo
10,960 Isaac Atsiyerọ, Ileṣa

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA
DI

**Omo Egbe Imole Owuro**

(Iwe idi ọmọ Ẹgbẹ)

Orukọ rẹ ____________

Adirẹsi rẹ: ____________

Ọmọ ilu ti o jẹ ____________

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akọwe Ẹgbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan

AKEDE ỌNA IYE

# E je ki a gbadura (2)

"MAṢE ikanra nitori awọn Oluṣebuburu, ki iwọ ki o maṣe ilara nitori awọn oniṣẹ ẹṣẹ, Nitori a o ke wọn lulẹ laipẹ bi koriko, nwọn o si rọ bi eweko tutu. Gbẹkẹle Oluwa ki o si maa ṣe rere, Maa gbe ilẹ na ki o si maa huwa otitọ". Orin Dafiidi 37, 1--3.

Iwọ ọmọ enia, jẹ ki o ye ọ l'oni pe, bi o ba gbẹkẹle ọlọrọ ti ko fẹ Ọrọ Ọlọrun, ani ti iwọ ba fi Ọlọrun silẹ ti o si fi ọlọrọ enia ṣe gbogbo igbẹkẹle rẹ: ranti pe, ọjọ kan mbọ ti ọlọrọ na ti o ti kọ ọrọ Ọlọrun silẹ yio ṣubu, ti iwọ ti o fi i ṣe agbẹkẹle rẹ na yio si ṣubu pẹlu.

Nitoripe nigbati ẹni ti enia ni ireti s'ọdọ rẹ ba ṣubu, ireti iru ẹni bẹẹ yio jasi ofo ni.

Ṣugbọn bi iwọ ba jẹ olododo ninu ipo yowu ti Oluwa to ọ si, ti o ko si yẹṣẹ kuro ninu ododo na, l'ọjọ ti igbi aiye ba de, a o gba ọ la gẹgẹ bi awọn ti o ba Noa wọkọ ni ijọsi.

O yẹ ki a beere, kini ohun ti o nfa iṣubu ọpọ enia paapaa awọn enia nla aiye yi lẹhin ti nwọn ba ti goke tan ?

Ohun ti o nfa a ni pe, awọn yapa kuro ninu ifẹ Oluwa Ọlọrun wọn. Ni akoko ti ipọnju ba wa fun ọmọ aiye yi ni nwọn maa nranti Ọlọrun ti nwọn si nwulo fun Ọlọrun; ṣugbọn nigbti nwọn ba di enia atata tan, ti aiye wọn si dara, nwọn a sọ Ọlọrun di ọta wọn. Eyi ko si yẹ ki o ri bẹẹ.

Nitorina, eto adura ti mo nṣe yi dara fun iwọ ti o wa ni ipo nla ki o ma baa pada di ẹni kekere, o si wa fun iwọ ẹnikekere ki o le de ipo nla. Nitori-na, ẹ jẹ ki a gbadura.

ADURA

Oluwa Alaanujulọ, o daju pe IWỌ ko fẹ iku ẹlẹṣẹ bi ko ṣe pe, ki o fi ẹṣẹ rẹ silẹ ki o si yipadi si Iwọ Ọlọrun Ẹlẹda wa.

Njẹ nisisiyi Oluwa, ma ṣai fi oju aanu wo mi lati dari gbogbo aiṣedede mi jin mi. Oluwa, jọwọ ma ṣai jẹ ki ẹmi ifẹ gbilẹ ni aiye yi ki imọtara ẹni nikan maṣe fi Orilẹ-ede wa jogun ki olododo ma baa pin ninu ijiya ẹṣẹ awọn ti eti wọn di si ọrọ Rẹ.

Oluwa, ma ṣe fi aiye mi sinu okunkun ki nle fi imọlẹ Iwọ Oluwa ṣe akoso ile mi ati Orilẹ-ede mi lai bẹru awọn ẹni okunkun aiye ti Iwọ Oluwa ko nii ṣai ṣe idajọ wọn ni gbangba.

Oluwa, jọwọ tan imọlẹ si okunkun aiye ki aṣiri gbogbo awọn oniṣẹ ibi okunkun aiye maṣe bọ ninu aiye yi titi opin aiye yio fi de.

Oluwa, mu mi lati ṣe ifẹ Rẹ ki o ma si ṣe jẹ ki ọda ohun rere da mi. Oluwa, jọwọ gbe mi leke gbogbo awọn ti araa wọn kọ otitọ; Ki imọ otitọ Rẹ jẹ agbara fun mi. Oluwa maṣe gba ero buburu awọn ti o nṣe inunibini si mi gbọ. Oluwa jọwọ fun mi ni ẹmi ifarada lati le maa lo aiye mi pẹlu ibukun Rẹ ti o nmu ni la lai fi laalaa kun un.

Oluwa, pese fun mi ni ọna ti ng ko fi nii ṣẹ agbara Rẹ. Ani Oluwa, jọwọ fi ẹsẹ mi le ọna iye ki ẹlẹbọ ma baa pẹgan mi.

Oluwa, ma ṣe jẹ ki ọrọ Rẹ ni mi lara lati gbọ, ma si ṣe iẹ ki ọrọ Rẹ ni mi lara lati mu lo ki eṣu ma baa sọ ọrọ Rẹ di ọta mi.

Oluwa, mo mọ daju pe, ko si ọna miran ti a o gba gba araiye la ju ọdọ Rẹ lọ; torina, jọwọ Oluwa, ma ṣe jẹ ki nfi aiye ba ọrun jẹ.

Oluwa, ma ṣe jẹ ki ogun eṣu bori igbagbọ Rẹ ninu mi. Oluwa ma si ṣe jẹ ki eṣu lo mi lati maa tako ọrọ otitọ Rẹ. Fi eti si ọrọ mi Oluwa ki O si kiyesi aroye mi ninu aiye yi ki ọda ohun rere ma ṣe da mi; nitoripe Iwọ Oluwa mi ki iṣe Ọlọrun ti inu Rẹ dun si ohun buburu..

Oluwa, jọwọ fi ayọ si mi ninu, ki eṣu ma baa fi ohun asan aiye yi sọ mi di alailera ọkan.

Oluwa, jọwọ fi oye ati ọgbọn kun inu awọn olukọ wa gbogbo ninu aiye ki awọn ọmọ wa ma baa ṣina ninu ẹkọ.

Oluwa, awọn Alaṣẹ wa gbogbo di ọwọ Rẹ: -Gomina, Akọwẹ Agba, Adajọ, Agbẹjọro, Ọlọpa, Ologun ati gbogbo awọn Olori ilu, Olori ile iṣẹ gbogbo di ọwọ Rẹ, jọwọ, fi aaye gba otitọ ati ododo l'Orilẹ-ede wa ki a le maa gbe igbesi aiye alaafia nitori JESU KRISTI OLUWA WA, Amin.

LATI ỌWỌ WOLI S. I. OWOẸYẸ



WOLI S.I. OWOẸYẸ
Oniwaasu naa.

# Odun Eegun dun ni Ogbaagbaa

IROHIN lati ilu Ọgbaagbaa ni agbegbe Iwo fi ye wa pe ọdun egungun dun ni ilu na ni ọdun yi nitoripe awọn egungun meji ti o leju-lọ ni ilu na fi pẹẹki ko pẹẹki.

A gbọ pe eegun na Gọgọru ti iṣe eegun Oluọdẹ ati Ṣokoti ti ṣe eegun Ogunleke Apena Ọgbaagbaa dan nkan wo ni igboro ni Ọgbaagbaa.

Irohin na sọ pẹlu pe kiifẹ-kiigba ni ọrọ awọn egungun na jẹ nigbati nwọn yari mọ araa wọn lọwọ ki o too di pe Alagbaa ba wọn pẹtu si iporogan na. Egungun ọdun na ti pari bayi.

# Ajala jade laiye

IROHIN lati ilu Jos ni Oke - Ọya fi ye wa pe Ọgbẹni Emmanuel Ajala ti iṣe ọkan ninu ọmọ Ẹgbẹ Alatiṣe ti kuro ninu aiye yi ni ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu keje ọdun yi, o si ti fi ilẹ bora bi aṣọ.

A gbọ pe Oloogbe Ajala jẹ ọmọ ile Ọdẹfara, o si jẹ enia rere, ati pe ọpọlọpọ enia l'o peju pesẹ nibi eto isinku rẹ.

Ara awọn alabakẹdun nibẹ ni Ọgbẹni Moses Ọlatunji ti iṣe Alaga Ẹgbẹ Alatunṣe, E. F. D. Alade, C. A. Akanbi ati bẹẹbẹẹ lọ.

# IWE ORO OLORUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkọọkan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kobo (50k) pere.

Awon Iwe na ni:

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JỌWỌ ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa. Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ,
Box 1206,
Ibadan.

BI o ba fẹẹ kọwe si Olootu, maa kọ ọ si; Olootu, P. M. B. 5230, Ibadan, Iwe na ko gbọdọ gun rara.

— OLOOTU

# Nję o mọ idi rẹ̀ ti aadọtaleloọdunrun ọkẹ 7,000,000 igo Guinness yio fi jẹ́ mimu loni?

Loni Aadọtaleloọdunrun Ọkẹ 7,000,000 igo Guinness ni ọmọ araiye yio ṣi, ti nwọn yio mu l'ãmugbãdùn.
Nitoripe ni Naigiria, ni Ireland (ibiti Guinness ti ṣẹ), ni Ilẹ Gẹẹsi, Trinidad,
Malaysia, Kenya, Cameroun, ati Ghana, nwọn npọn oti Guinness lọwọlọwọ bayi.
Awọn enia mbeere fun Guinness lọwọlọwọ bayi.
Guinness ni ọti ti atayebaiye pọn. Jakejado aiye ni awọn enia ti mọ bi Guinness ti dara to.
Igbadun inu Guinness, agbara inu Guinness, ti di mimọ̀ fun gbogbo aiye lati bi igba ọdun s'ẹhin.
Lojoojumọ – bi ilẹ ojo kọọkan ti nmọ̃ – 7,000,000 ife Guinness ni awọn enia ngbẹ́yẹna, ti nwọn mu l'ãmugbãdùn.
**Fi igo kan tirẹ kún un, k'ó di 7,000,001?**

## GUINNESS dara pupọ, fun ọ



# Saka di Mogaji Olugbode

Ni ọjọ Isinmi ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu kejọ odun yi ni Alagba Saka Olugbode ṣe ajẹyọ riro ti o role Baa'ẹ Olugbode ni agbo ile Olugbode Ibadan ni ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu keje ọdun yi lati (w) Olubadan Ibadan Alayeluwa Ṣitu Oyetunde keji.



ALAGBA SAKA OLUGBODE
Mọgaji ile Olugbode.

Mọgaji titun na ni o role lẹhin iku Oloye Samuel Adeọjọ eniti o ku ni ọjọ kẹtala oṣu keje ọdun ti o kọja.

Eni ẹdun mejidelaadọta ni Mọgaji titun na iṣe. O gba iṣẹ jagunjagun ninu ọdun 1941 si 1945, lẹhinna ni o fi iṣẹ jagunjagun silẹ ti o gba iṣẹ Ọlọpa Eko ninu ọdun 1949 si 1959.

Lẹhin ti o fẹhinti nibi iṣẹ Ọlọpa ni o bẹrẹ sii ṣowo, ti o si nṣiṣẹ alagbaṣe ile (Building Construction) eyi ti o nṣe lọwọ titi o fi bọ si aaye awọn Baba rẹ na.

Ni ọjọ ajọyọ yi Mọgaji ra fi jijẹ ati mimu tẹ awọn ti o wa sibe lọrun nitoripe ajẹti ni onjẹ, emeti si ni ọti Ero pọ bii rẹrẹ.

Diẹ ninu awọn alaḳaṣẹyẹ ọjọ na ni Oloye Kọlẹẹṣọ Oludari ile-iṣẹ Itura Liṣabi Club lati Eko, J. O. Adebiyi, Karimu Lawal, Amusa Adedapọ, Lamidi Ṣanusi, Ladeji Adio, N. A Onis'niyan, Iyaafin Misitura Akintọla, Alhaja Ọwọade ati Alhaji Amusa aburo Mọgaji.

Elere ọjọ na ni Adegbindin ati Adediji Ajani Onilu -- Ṣẹkẹrẹ

# Alhaji komo Alarape

Ni ọjọ karun oṣu kẹjọ ọdun yi ni Olọrun ti ọmọkunrin kan fa Alhaji Akibu Alarape lọrẹ ni agbo ile Fọkọ nilu Ibadan.

Ni ọjọ kejila oṣu yi ni nwọn si ṣe ayẹyẹ ikomọjade ni ile wọn kanna nibiti ọpọlọpọ enia lẹbi, l'ọrẹ lojulumọ pese si.

Alhaji Raufu Mọgaji Imam Oke - Gegọ pẹlu Alhaji Karimu lati Ilọrin l'o ṣeto isọmọloruko na gẹgẹ bi ilana ẹsin Islam

Oruko ti nwọn fun ọmọ na ni Ibrahim Ọmọwale Ayinla Alarape.

# Ijo Apostolic Sajodun

Ni ọjọ kọkanla oṣu kejọ ọdun yi ni Ijọ Apostolic Oke Oluwatẹdo Apakẹe ni adugbo Tara, Ogbomọṣọ, ṣe ajọdun kẹfa ti nwọn da Ijọ na silẹ nibẹ. Alamojuto gbogbogboo fun Ijọ na Evangelist P. Anifowoṣe l'o ṣe adari eto na.

Alufaa Itabiyi ti Ijọ God Blessed ni adugbo Kiatika, Ogbomọṣọ l'o ṣe akanṣe iwaasu nibi ajọdun na, awọn ẹgbẹ Akọrin lati Ipinlẹ Ado-Ibinni fi ede Ibinni kọrin pataki kan l'ọjọ na.

Awọn adari Ijọ na ti o ṣeto ajọdun na ni: D.K. Okẹ, David Adeyẹmọ, J.O. Ayantọla, David Ọyawale ati Evangelist Anifowoṣe.


**KERE O! KERE O!!**

**Bi o ba je onisowo ti o nfe ki oja re maa ta; ti o si nfe ki oja re gbajumo kari aiye gegebi iwe irohin IMOLE OWURO ti gbajumo; darapo pelu awon enia atata ti o npolowo oja won sinu Imole Owuro.**

**Fun alaye ekunrere nipa bi o se nilati se e ati iye ti o nilati san; wa sile ise wa tabi ki o kowe si:**

**Advertisement Manager**
**(Imole Owuro)**
**N4/496B Yemetu Aladorin**
**P. M. B. 5230**
**Ibadan.**



**38**

IWE IGBAẸLODE DARA PUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 10k
2. Kurani esu marun Yoruba 55k Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (15k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (50k) Iwe Eniaṣoro (50k)
7. Adedẹwẹ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1.50)
10. Kekere (30k)
11. Iwe Oogun iwosan (N1.5) Kekere (45k)
12. Itan Anabi ati Yisa (55k)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odo—ye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.



(2) Alufa Igbaẹlode, Mọsalaṣi Idi-Iṣin St, Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin.

# KI LO SELE?

## Ọmọ Igbo - Ọra fee pade

NI Ọla ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kedọgbọn oṣu yi ni ipade oloṣooṣu ti awọn ọmọ Ibilẹ ilu Igbo-Ọra ni ẹkun Ibarapa ti nwọn ngbe ni ilu Eko ati agbegbe rẹ yio waiye ninu ọgba ile iwe Saint Jude's ni Ebutemẹta.

Ẹniti o sọ eyi di mimọ fun Onirohin wa ni Akọwe ẹgbẹ ọmọ Ibilẹ Igbo-Ọra Eko, Ọgbẹni J. O. Ige; o ni ipade na yio bẹrẹ ni deede agogo mẹta ọsan.

Ọgbẹni Ige kesi gbogbo ọmọ Igbo-Ọra ti o mbẹ ni ilu Eko lati tete de sibi ipade pataki yi fun ire ati ilọsiwaju ilu abinibi ẹni, nitori "ile ni abọsinmi oko".

## EGBE IJINLE YORUBA EKO YIO PADE

IPADE oloṣooṣu ti Ẹgbẹ Ijinlẹ Yoruba, Eka Eko yio waiye ni ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu yi ninu ọgba ile iwe Saint Jude's Ebutemẹta labẹ Alaga Ọjọgbọn Adeboye Babalọla ti Yunifasiti Eko.

Irohin fi ye wa pe, ni deede agogo marun abọ ni ipade na yio bẹrẹ.

Akọwe ẹgbẹ na waa rọ gbogbo ọmọ ẹgbẹ lati tete de, ki nwọn si mu ọrẹ, ojulumọ ati ẹbi wọn wa pẹlu fun ilọsiwaju ede ati aṣa ibilẹ Karọ—Oojire.

## Jonathan Ojo saisi

O to ẹgbaa enia ti o pesẹ sibi isin iranti ti o galọla kan ti nwọn ṣe fun Alagba Jonathan Popoọla Ojo ni ile Ọlọrun Ijọ Onitẹbọmi Ipẹẹ l'ẹkun Ọyun ni Ipinlẹ Kwara, eyi ti o waiye ni ọjọ kọkanla oṣu kẹjọ ọdun yi.

Ni ọjọ Isinmi ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu keje ọdun yi ni Alagba na filẹ bora bi aṣọ.

Alufaa Ẹni-ọwọ J. F. Muyiwa ti Ijọ Onitẹbọmi Ipẹẹ sọ pe iku Oloogbe na dun oun jọjọ, ṣugbọn oun ni itunu nitoripe o jẹ Onigbagbọ ododo.

Alufaa na sọ pe igbesiaiye Oloogbe na yẹ ni awokọṣe ati ipenija fun "awa ti a ku l'ori ilẹ aiye nitoripe ki iṣe ọdun gigun ti a lo laiye l'o ṣe pataki bikoṣe bi a ba ti lo iwọnba ti Ọlọrun ba fun wa na si"

Alufaa na mu ọrọ ti Oloogbe na sọ ninu ẹkọ awọn olukọni laipẹ yi wa si iranti.

O ni nibi ipade yi ni o kesi awọn akẹkọ lati maa kiyesi ohun ti ọrun ju ti aiye lọ eyi ti Alufaa na sọ pe o yẹ ni ohun ti olukuluku enia ki ba tẹle.

Irohin fi yc wa pe oniruuru eto alarinrin bii kika oriki orilẹ Oloogbe na ati orin akanlẹ-kọ lati ọdọ Ẹgbẹ akọrin l'o waiye.

Ara awọn ti o ṣeto wọnyi ni Diakoni Elijah Ọlalẹyẹ, James Amọo, J. L. Fatoki lati Ọfa, M. O. Ogunlakin ati bẹẹbẹẹ lọ.

Ogbologbo onilu Sakara ni Oloogbe Ojo nigba aiye rẹ; lati ọdọ ni o si ti lọ silẹ Aganyin nibiti o ti nlu sakara titi di ọdun gbọọrọ sẹhin ti o pada wa si Ipẹẹ ilu rẹ.

Lati igba ti o ti pada sile, oun ni o maa nlu fun ẹgbẹ akọrin Ipẹẹ. O lo to aadọta ọdun l'aiye; iyawo meji ati awọn ọmọ l'ọkunrin lobinrinl'o fi s'aiye lọ.


## ORIRE FUN ARANSOTA

A fi eyi kede fun gbogbo awọn Aranṣọ (Tailors) jakejado Orilẹ-ede yi pe, a ni ẹrọ ti o nṣe bọtini alaṣọ pẹlu oruka goolu leti rẹ (Dies mouls and Gold ring) ni oriṣiriṣi fun tita bayi.

Bakanna ni a tun nta ẹrọ ti nfagi ti o si nlagi.

Ẹ maa bọ taara ni:-

G. ADEWALE & SONS (NIG.) LTD.,
5, GEORGE STREFT,
ṢOMOLU VIA APATA,
LAGOS STATE.



Tabi ni:-

*29, NEW - COURT ROAD
IBADAN

Tabi ni:

*65, FOLAGBADE ST., IJEBU--ODE

Tabi ni:

*14, IGBIN ST., WARRI
MID--WEST.


# IWE SI OLOTU

## Ojẹ l'o nyọ!

Olootu,

NINU Imọlẹ Owurọ nyin ti 17/8/74 ni mo ti ka a ti ọkunrin kan ti o pe araa rẹ ni Afanda Afariẹnigoṣoogun ti nkesi Ọlọla Atioro pe ki o maa bu awọn ọlọmọge ti o mba aiye jẹ.

Bakanna ni mo ka atilẹhin ti o fun Ọlọla Atioro pe ki o ma bẹru bi ọrọ eebu na tilẹ la ti Ọlọpa tabi ile ẹjọ la nitoripe oun mbẹ lẹhin rẹ.

Ni t'emi, ng ko jẹ gbẹkẹle iru ileri yi, mo lero pe Atioro paapaa si gbọn ju ẹniti yio gbẹkẹle iru rẹ nitoripe l'oju temi, "Ojẹ l'ọkunrin na nyọ".

Emi ni,
Iyiọla Ijadun,
Eko.

AKIYESI

Ọlọla Atioro tiwa kii bu enia. Bi o tilẹ jẹ pe otitọ ọrọ ti o maa nsọ le jọ eebu l'oju ẹlomiran, ikilọ ni Atioro maa nṣe; a si maa ro ti ofin ti ọmọ enia fi nde araa wọn mọ ọrọ rẹ.

— OLOOTU


## ARA NFAAJO




"PIRI l'olongo nji a ki i ba okunrun ẹiyẹ l'ori itẹ" Fun agbara akọtun lojoojumọ, maa lo MAGNATONE TỌNIKI.

Beere ni ile itaja adugbo rẹ tabi ni:

BASOTO PHARMACY,
63, IDUMAGBO AVENUE
LAGOS.



## OJA OPO

ILE-IṢOWO M. A. AGBEJINMI & SONS ti o wa ni Opopo Laoye, Itapopo, Ogbomọṣọ ni awọn oriṣiriṣi ọja bii Matirẹsi, Kuṣin, Irọri (cushion pillows), Ibusun onirin, ohun elo ikọle ati bẹẹbẹẹ lọ fun tita ni ẹdinwo.

Maṣe jẹ ki anfani yi fo ọ ru, waa ra tirẹ l'oni.

M. A. AGBEJINMI
(Alakoso)



## Toyin Bookshop

FUN ẹdinwo ati ẹbun ọfẹ, waa ra iwe rẹ ni : TOYIN BOOKSHOP,
Takie Sq,
Ogbomọṣọ,
Phone 90.

# Ile ejo gbe Ọmọ fun Alhaji Oba

ILE ẸJỌ keji Onipo-keji ni ilu Ilọrin ti da Alhaji Ọba, ọmọ ile Oni-lu ni adugbo Alanamu nilu Ilọrin l'are pe oun ni baba ọmọ ti oun ati iyawo rẹ tẹlẹ Riyamatu Abẹbi ti ile Yerefu Ilọrin mba araa wọn ro.

Ni ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu kejọ ọdun yi ni nwọn ṣe ida-jọ ẹjọ na. Ẹni ti Alhaji Ọba pe l'ẹjọ ṣikeji ni Alufaa Amọsa ti o kọ Alhaji Ọba silẹ.

Ẹjọ ti Alhaji Ọba pe obinrin na ni pe, o gbe oyun oun lọọ fẹ ọkun-nrin miran.

Ṣugbọn nigbati nwọn nrojọ na lọ, obinrin na sọ pe oun ko gbe oyun Alhaji Ọba lọ ni-toripe oun ko tii lo-yun ti oun fi kọ ọ silẹ, ati pe lẹhin ti oun kuro nile rẹ, oun gbe oṣu mẹrin gbako nile baba oun ki oun too lọọ fẹ ọkunrin miran.

Ṣugbọn ẹlẹri rẹ sọ pe obinrin na ko gbe ile baba rẹ gẹgẹbi o ti wi.

Ninu idajo rẹ, Adajọ ile ẹjọ na Ọgbẹni A. S. Na-Allah sọ pe; oun ti woye ẹjọ ti awọn mejeeji ro niwaju oun, oun si ri i pe oyun ọkọ rẹ l'o gbe lọ si ọdọ ọkọ titun ti ti o fẹ na.

Nitorina, Adajọ na da obinrin na lẹbi, o si paṣẹ pe ọmọ na ti o di ọdun kan ati oṣu meji jẹ ti Alhaji Ọba lati ọjọ na.

# "EDA" titun gbere de !

GBAJUMỌ alare arinjo kan ni Ilẹ Naijiria Ọgbẹni Lere Paimọ ti inagijẹ rẹ njẹ ẸDA ONILẸỌLA, yio gbe are nla kan jade ninu oṣu kẹsan ọdun yi.

Are na ni o pe ni "OGBORI--ẸLẸMỌṢỌ" Ni ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu kẹjọ yi ni o ṣe are na wo ni-waju awọn aṣoju ile iṣẹ iwerohin gbogbo ti nwọn mọ nipa are iṣẹdalẹ.

Koko ohun ti Ọgbẹni Lere Paimọ ati awọn ọmọlẹhin rẹ fẹẹ fayọ ninu are na ni ohun ti o fa orukọ na "OGBOMỌṢỌ" ti a fi npe ilu t o tob ṣi-keji ni ilẹ Iwọ-Oorun; ati pataki ninu ilu ologun ilẹ Yoruba ni aiye atijọ.

Lẹhin are na, awọn onirohin kan saara si Ọgbẹni Lere Paimọ pe o mọ are na iṣe pupọ ati pe o ṣoro fun awọn lati ri alebu sọ si i.

Onirohin wa ti o wa nibẹ sọtẹlẹ nipa are na bayi; "Mo woye pe bi Ẹda ba nṣe bayi gbe are na jade, are "OGBORI--ẸLẸMỌṢỌ' yi ni yio fa owo wọle julọ, ti yio si mu okiki wa julọ fun Ẹda ninu awọn are ti o ti ṣe ṣaaju".

# Elejigbo

(Lati Oju Ewe Kinni)
ko tilẹ tanmaa pe ẹ le ka wa yẹ kun ẹni ti ẹ ba bẹwo nitoripe alai-lọla ṣa ni awa iṣe".

Olootu na fi kun un pe, ohun oriyin gbogbo ti Ọba na sọ nipa iṣẹ oun ki iṣe agbara oun bikoṣe oore-ọfẹ Ọlọrun, o si gbadura pe "bi Ọlọrun ṣe nran wa lọ-wọ lati maa ṣiṣẹ wa ti awọn enia fi nfẹ wa, bẹẹ gẹgẹ ni ki o lee wu Ọlọrun lati ran nyin lọwọ ki ẹnyin na le lo itẹ nyin, ki awọn enia si le maa fẹ ẹnyin na pẹlu".

Lẹhin ti a mu Ọba na yi ẹlẹkajẹka ibi iṣẹ wa tan ni o pada si ori itẹ rẹ ni Ejigbo.


## Jovial Nap

Nap 2, 9, 40
Perm 1, 14, 21, 22, 28
If Q.P.R draws at no 9 come for 3 sure draws in week 5-
M. O. Oketọna
15 Oke Ọla St
Apomu--Ikire
9xxbk

**8, 16, 50**



# OLORIRE O ! OLORIRE O !!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LIMITED

TI A JẸ OJOGBON PATAKI
NIPA ONIRURU ẸRỌ.
AWA NI A NKE SI NYIN PE:
A TI GBE T'ANA DANU,
A TI GBE OMIRAN DE:
A TI NI ẸRỌ ALAGBARA—NLA KAN
TI ORUKỌ RẸ NJẸ



## Circular Saw Bench

**(With 36" Blade) = N600·00**
**24" Blade = N340·00**

(EYI NI ẸRỌ ILAPAKO)

Awọn onişowo nlanla
Ti nwọn ti ra ẹrọ na ṣaaju
Ni o ti nkọwe iki – ni si wa
Pe, bi a ti nrohin ẹrọ na
Ni awọn ba a.
Iwọ na ma jafara l'oni

Bi o ba fẹ ire fun araa rẹ.

Owo ẹrọ na ko pọ, N600 . 00 pere ni o ni 36" Blade
N340.00 si ni o ni 24 "Blade.
Ki iṣe iru ẹrọ yi nikan ni a ni.
Orişirişi fun oniruru iṣẹ ni o mbẹ pẹlu,
Bakanna ni a si ni ẹrọ ilọta "BECCO"

Ma jafara mọ,
Tete maa bọ pẹlu 'Imọlẹ Ow urọ' kan ti a
polowo ẹrọ yi si ninu si:

## *Western Nigerian Technical Company Limited,*

P. M. B. 5148; PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.


Printed and Published by The People's Star Press Ltd, N4/496B Yemetu Aladọrin P. M. B. 5230 Ibadan Olotu (Editor) Lawuyi Ogunniran